## Ìdzɛ̀sí-mi bɔ̀lɔ̀ndzɔ̀dzɔ̀ɔ̀!

Ìdzɛ̀sí-mi bɔ̀lɔ̀ndzɔ̀dzɔ̀ɔ̀!
Ìdzɛ̀sí-mi, kí màa dzɛ gbàgbé-ɛ̀ɛ ná!
Ìdzɛ̀sí-mi, àŋgbɛ̃-ɛ̀kɛ́ nàmí kí!
Ìdzɛ̀sí-mi, bí ǹ tédzú-ɛ̀ɛ, ebi kà kpa mí ró!
Ìdzɛ̀sí oláàtɛ̀dzú gbɛ̀wùù bóɖò kɔ̃́!
Ìdzɛ̀sí olóòkpì ɖɛ̀ɖɛ̀ bóòdzò tsú!
Ìdzɛ̀sí olɔ́mɔ́ gbɔ̀rɔ̀ɔ̀ bɔ́ɔ̀gbɔ̀gbɔ́!
Ìdzɛ̀sí dzàràà nɔ́wɔ́ bíìgbá!
Ìdzɛ̀sí olɛ́ɛ̀kɛ́ bí àɖó!
Ìdzɛ̀sí, ɛ̀kɛ́ ní kpòwé si bɛ́ɛ̀ ɛ́!
Ìdzɛ̀sí olényí báwò ká ń rĩ́rã!
Ìdzɛ̀sí olásɛ̃́ bíìdzèwe!
Ìdzɛ̀sí olóòkpì bóògèɖe!
Ìdzɛ̀sí-mi bɔ̀lɔ̀ndzɔ̀dzɔ̀ɔ̀!
Ìdzɛ̀sí-mi, ò má dzɔ́ɖò, ǹ má ɖomi, tsí gbé ńnɔ́-ɛ̀ɛ!
Ìdzɛ̀sí-mi, ò má dzɛ́ lalá, ǹ má ɖàɖɔ̀wé (ɛyɛ-lálá), tsí wà rɛ̃̀ náànyì-ɛ̀ɛ!
Ìdzɛ̀sí-mi, ò má dzágo, ǹ má ń so, tsí wà ń yɛ̀wò wérí!
Ìdzɛ̀sí-mi, bí ǹ ríɛ nóòtèrè fee, ara-mi náa fírì si kpó gé ni!
Ìdzɛ̀sí-mi, má réré se dzídzɛ ró!
Ìdzɛ̀sí-mi, bí ǹ ríɛ gé ná, mà ti yó!
Ìdzɛ̀sí-mi bɔ̀lɔ̀ndzɔ̀dzɔ̀ɔ̀!